# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 860 . LAGOS SARTUDAY MARCH 9th—MARCH 15th 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


EYI ARA!

# Opo Kan Gba Egbesan Ponun Lori Obe T'ose F'oko Fun Odun Merinlelogun

TORONTO (Canada)—Ni igba gbogbo ni a ti ma ngbọ orin "ỌLỌBẸ LO NI Ọ K Ọ" lọdọ awọn orogun meji ti nwọn ba nkọrin ni arin ile, iru ọrọ orin bayi ni a gbọ wipe o ko orire ba obinrin Oyinbo opo kan ni ijẹta ti orukọ rẹ njẹ Ruth Marice, alarede ọkunrin kan ti o jalasi ti orukọ on na njẹ Rowe ni ilu Hamilton ni Canada nişe.

Ẹni ọdun mejidinlọgọta ni opo obinrin yi. A gbọ wipe lẹhin ti ọkọ rẹ ti o gbe e ni arede ti jalaisi ni o pade ọkunrin alabakẹdun kan, Albert A. Beckitt, opo ọkunrin ni on paapa nitoripe iyawo ti on na fi oruka fun ti jalaisi.

Ko-lọkọ wa pade ko-laya, awọn mejeji wa fi ohun sọkan lati ma rin pọ ni irin ko jọ iyawo ko jọ ọrẹ, sugbọn opo obinrin (Ruth) npata si Albert lẹnu lasiko lasiko, o si mba a ko awọn asọ rẹ sọpan, o nfọ wọn mọ fun un.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

## Bisobu Howells Jalaisi L'Eko

EKO — A gbọ ju'gba nu ni iku Ẹniọwọ Ọgbẹni Adelakun Williamson Howells, tişe olori gbogbo awọn bişọbu Ijọ Ṣọsi CMS ni Nigeria ti o jalaisi ninu ile rẹ ni Ẹhingbẹti loru ana.

Ẹni ọduu mẹtadinlọgọta ni Bişọbu Howells o si jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ologbe Bişọbu A W Howells ni Erunwọn ni Abẹokuta. Ilewe giga CMS Grammar School ati King's College l'Eko ni o ti ka iwe ki o to lọ pari ẹkọ rẹ nani SARO (Sierra Leone), o si fi ọdun gbọrọ kọ nwọn lẹkọ ni ilewe giga Awka (Training College) leti Onitsha, lẹhin eyi o tun şe işẹ tişa ni ilu baba rẹ ni Abẹokuta Grammar School.

O si tun fi igba kan şe igbakeji ọga ilewe-giga Fourah Bay College ni Saro ki o to pada si Eko gẹgẹbi Alufa Ṣọşi Arọloya


## LAGOS RACE CLUB

LAST DAY

February Race Meeting
On Saturday 9th March, 1963.
First Race at 3.30 p.m.
The Guest of Honour is
His Highness Sir Adeniji Adele II
The Ọba of Lagos.


AKINTỌLA ATI ADEGBE RO:

## Nwon F'enu Kan Ejo Won Ni Kotu Ilu Oyinbo

LONDON — Ẹjọ ko tẹ-mi-lọrun ti Alhaji Dauda Adegbenro fi igba kan pe wipe on ni ipo Olotu Ijọba Iwọ Orun tọsi kişe Oloye S.L. Akintọla ti nwọn fi ọtẹ gbigbona yọ, ni awọn ogunna-gbongbo adajọ ile-ẹjọ ti o ga ju lọ (Privy Council) fẹnu ka ni ilu Oyinbo ni owurọ ijẹta. Lọya agbẹjọro awọn mejeji, Alhaji Adegbenro ati Oloye Akintọla ni nwọn si fi tara tara sọrọ nibẹ.

Lọya ti o kọ sọrọ niwaju alaga igbẹjọ na, Ọlọla Evers'ied, ni Ọgbẹni Dingle Foot ti Alhaji Adegbenro gba; Lọya na ni on fẹ ki awọn ogunnagbongbo adajọ yi tete gbọ ẹjọ ti on tẹ ro lori ofin ti nwọn fi yọ Oloye Akintọla kuro lori aga Olotu Ijọba Ipinlẹ na.

Lọya na ni on fẹ ki nwọn tete gbọ ẹjọ na ki awọn le mọ bi otitọ ni Ọba Aderẹmi, Ọni Ile Ifẹ tişe Gomina Ipinle Ijọba Iwọ Orun nigbana ni agbara lati yọ Olotu Akintọla tabi o di igba ti awọn aşoju ti nwọn yan sile igbimọ ba dibo ninu ile na wipe awọn ko fẹ mọ.

(Wo iyoku loju ewe keji)

## Awolowo Yio Dahun Gbogbo Esun Re Pelu Awon Ogun Enia Ti O Ku Ti Ijoba Mba Rojo

EKO — Kotu ganran ni ọdan ko gba ẹsẹ fun ogunlọgọ awọn enia, lọmọde lagba ti o wa ibẹ lati gbọ nkan ti adajọ yio wi nipa Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu awọn mọkanlelogun kan ti awọn Ọlọpa mba şe ẹjọ wipe nwọn dite si Ijọba, nwọn fẹ fi agbara gba Ijọba, ti nwọn nro a-ro-jare wipe ki adajọ da awọn silẹ ko si ọro ninu ẹjọ ti awọn Ọlọpa mba awọn şe rara.

Gbara ti adajọ na, Ọgbẹni G S Sowẹmimọ, ti gun ori aga ni owurọ ana ti nwọn si ti pe ẹjọ na ni adajọ na si ti fi abẹ gee pe, on ti ro gbogbo ọrọ ti nwọn ro niwaju on, on si ri pe gbogbo awọn arufin na ati Oloye Awolọwọ ni nwọn ni lati dahun gbogbo ẹsun ti awọn ọlọpa ka mọ wọn lẹsẹ patapata.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Ejo Akintola Ati Adegbenro Nilu Oyinbo

(O bere loju ewe kinni)

Oyinbo agbejoro (Dingle Foot) tun se alaye fun awon adajo na wipe nkan ti o se ti awon ko fe ki nwon ma fi a ti gbejo na d'oni d'ola ni pe a ti se eto inawo ododun ti Ijoba ma nse ku si dede. o si ye ki Ijoba ipinle na ni Olotu kan pataki.

Ogbeni S N Bernstein, loya agbejoro fun Oloye Akintola paapa dide, o ni oro t'on ko po, on si faramo wipe ki nwon tete gbo ejo na sugbon ori nkan ti olin idasile ise Ijoba (Constitution) ilu Nigeria wi ni awon duro le lori pe ona ti nwon gba fi yo Oloye Akintola gege bi Olotu Ipinle Iwo Orun ko ba ofin mu rara Ogbeni Bernstein ni Oloye Akintola si ni gbogbo enia mo ni Olotu Ijoba na di ojo oni.

Ju gbogbo re lo Olola Evershed tise alaga ile igbejo na ni o wu awon ki awon tete gbo ejo na sugbon awon ko le ti gbo ni ijoko yi nitoripe ise kun owo awon. sugbon awon yio gbiyanju lati le gbo ejo ti t'otun tosi awon elej na fe ro nitu ijoko igbejo awon ti awon yio se ni osu meta (May) loni.

ENIA MEJI KU BAMU-BAMU

## Ategun Fagi Ya Nilu Ilorin

ILORIN – Opolopo ile onile ti mbe nilu Ilorin ni ategun nla kan ti o ja laipe yi gbe lo tarule torule, o si tun fagi ya soju ona kakiri; emi ati nkan ti o sofo lori ategun na ko kere rara.

Onirohin wa ni to itinwo enia ti jamba ategun na so di alainilelori ati omhobo. Eyi ti o tile buru nibe ni awon enikan ti nwon pe wipe ki nwon ba won kan pamu orule, ti ategun na gbe jumu lati orule ti awon ti nsise lowo, ti awon na tun di enikoosi.

Gbogbo awon enia ati iyawo ti nwon ni awon enia ti nwon lo si ibi ise ti nwon ko ri won ki nwon pada sile lojo na ni nwon wa awon enia won lo si ile awon gbokugboku ni ile alaisan lati lo wo bi enia awon ba wa ninu awon oku ti nwon ko lo sibe.

Oba Ilorin paapa, Mallam Sulu Gambari, wa ninu ara ilu ti o bora sile lati se ise lojo na. Olorun gba wa lowo ategun buruku.

## Nwon Gbe Obinrin Oselu Lo Si Kotu Fun Gbese

EKO — Obinrin oselu k omo egbe Olomi (NPC) ti oruko nje Ester Amusan ni a gbo wipe awon onigbese re awon Oyinbo kan ti nwon nje Bentworth Finance Limited ti o je ni ponun mokanladinlegbeje (£1.389.3'3d) faa lo si waju adajo agba wipe awon fe gba owo awon.





GET AROUND BETTER-TRAVEL

Lambretta

2nd SERIES 150 Li .......... £145
'SLIMSTYLE' 150 Li .......... £162
'SLIMSTYLE' 175 Tv .......... £175

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (T.B) • IBADAN • KANO • KADUNA • JOS • PORT HARCOURT • ABA

### "Olofintoto" Eleti-Ofe Nfi Oju-Agba Wo

# Oro Awon Osise Oko To Di Koko (3)

IṢẸ BINEY

Ni ọsẹ kẹta sẹhin nigbati mo bẹrẹsi kọ nkan silẹ lori awọn osiṣẹ idi ọkọ elefin ni Eko ati Apapa ati bi nwọn ṣe da iṣẹ a-npe-alaru-fọkọ ni ilu Eko ati pe tani akọwe ti o wa labẹ awọn Oyinbo onişowo ti o kọ bẹrẹ iru iṣe bẹ, nko mọ wipe Ọgbẹni wa, oloye W. H. Biney ko ni duro ka awọn nkan ti mo kọ nipa akikanju rẹ na.

Mọ ni lati awọn ilu ti nwọn wa ni agbegbe ILỌRIN bi Ologbondoko, Gamna, Ila, Omupo, Omu-aran, Ajasẹpo ati bẹẹbẹ ni nwọn ti nri awọn osiṣẹ yi ko wa s'Eko wa wọ iṣẹ niti Biney. Ẹniti iṣẹ tirẹ ko ba ti bọ si, a ma ba wọn wa ọkọ oju omi lọ si Ẹpẹ ati Ejinrin.

### A Se Kara

Mo mọ ọpọlọpọ ti nwọn ti di onile ọlọna ni igboro Eko ninu awọn ọmọ Ajasẹ-po tabi awọn ilu ti o wa ni agbegbe Ilọrin lọjọ oni ti o jẹ wipe iṣẹ "AFOKE AFI GBO" yi ni nwọnfi bẹrẹ ọla wọn. Emi ko fi eleyi bu wọn tabi lati fi ta abuku fun wọn nitoripe iṣẹ ni ogun iṣẹ, ẹniti o ba si jale ni o ba ọmọluwabi jẹ.

### Ogun Keji

Nigbati ogun ajakaiye ti awọn Oyinbo Jamani dasilẹ de, gbogbo ọja bẹrẹ-si wọn, awọn orişirişi ọkọ oju omi ni nwọn si nwọ ilu lati wa ko nkan ija ogun. Eleyi si jẹ ki awọn Oyinbo ọlọkọ sọ fun Ologbe Biney wipe awọn fẹ awọn lebira si ti nwọn yio ma ṣe iṣẹ lọsan ati loru ni ebute Eko ati ti Apapa.

Bi nwọn ti gba awọn enia si iṣẹ na to bẹni nwọn si bu owo diẹ si owo ti nwọn nsan fun wọn. Emi ko fẹ ki ẹ şi mi gbọ rara, owo-oşu kọ ni nwọn nsan fun awọn ara wa na, owo-ojumọ (daily paid) ni wọn nfi rẹ wọn ni ika.

### Alamodi

Ọjọ ti o ba s'amodi, ti o ko wa ṣe iṣẹ a ṣe kara, o ko ni epinni owo-iṣẹ lọjọ na rara. Bi o ba ṣe aisan fun ọjọ meje, a jẹ wipe o keran aşamegun; lọgan ni awọn ọga lebira a gba ẹlomiran dipo rẹ, iwọ alara paapa ni lati ma wa ọna ti wa ma pa amọdi yẹn mọra, ki o le tete pada si'bi iṣẹ nitori owo aladalu (ẹlẹwa) ti wa fe san.

Nigbati o ya, awọn ti nwọn ti jẹ ọga lẹnu IṢẸ BINEY yi ri wa nya iṣẹ ti nwọn; nwọn nlọ sọdọ awọn Oyinbo wipe awọn na fẹ ki nwọn ko ma gbe iṣẹ fun awọn, awọn yio ri ri awọn lebira ko wa s'ebute fun iṣẹ na.

### Eja Tuntun

Eleyi wa jẹ ki awọn oşiṣẹ paapa wa fura, nwọn si ṣe akiyesi wipe "OWO MBẸ LẸSẸ ODO" ni iṣẹ na; awọn na wa da ẹgbẹ ki iya ma jẹ wọn silẹ nwọn si gba awọn akọwe sidi ẹgbẹ na lati ma fi nkan ti o ba ndun wọn seti igbọ awọn onişẹ yi ki nwọn le gba ọrọ wọn ro.

Nkan ti o fa a ti ọrọ a nfẹ owo si ti nwọn ja si fifi idi jalẹ, ma sọ fun yin ninu alaye ọrọ mi lọsẹ ti mbo. Ki ẹ tete fowo pamọ lati ra Eleti-Ọfẹ ninu ọsẹ ti mbọ.

# Irohin Lati Ariwa Wa

## (Lati Owo Mallam Shewu)

Inu wa dun pupọ lati sọ fun ẹnyin ti ẹ nka iwe irohin Eleti-Ọfẹ ni oşọsẹ wipe lati inu ọsẹ ti mbọ ọkan ninu awọn akọwe onirohin wa ti orukọ rẹ njẹ MALLAM Shewu yio ma fi irohin awọn nkan ti o şẹlẹ kakiri ipinlẹ Ariwa ni Oke Ọya ranşẹ si wa, a o si ma tẹ awọn irohin na jade fun yin lọsọsẹ.

Mallam Shẹwu jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Oke Ọya li o kọ ẹkọ jinlẹ şugbọn lati igbati o ti fi ile ẹkọ silẹ iṣẹ a nkọwe fun awọn oniwe irohin ni o nṣe, o si jẹ ọkan ninu awọn ti o ma nka iwe wa lati igbati o ti nlọ si ile ẹkọ.

Gẹgẹ bi ọrọ on alara paapa: "Mo ṣe akiyesi wipe irohin ti o ba jẹ mọ Ipinlẹ Iwọ Orun nikan ni ẹ ntẹra mọ lati ma tẹ ja-de fun awọn ọkawe yin. Ọpọlọpọ nkan ni o nşelu lojojumọ ni Ipinlẹ Ariwa ni ilu bi Kaduna, Jos, Za-ria, Ilọrin, Minna, Kano, Maidugiri ati bẹẹbẹ lọ ti o yẹ ki ọpọlọpọ awọn enia ma ri wọn ka ti nwọn ko ri nwọn ka.

"Fun apẹrẹ, nwọn ṣẹṣẹ da ile-iwe giga kan, iru ti Ibadan, silẹ ni Zaria ti nwọn npe ni Ahmadu Bello University ọpọ-lọpọ awọn Obi ti nwọn jẹ ara Ipinlẹ Ariwa ti nwọn nsişẹ l'Eko ni nwọn ko mọ nipa ilewe giga na sugbọn nigbagbo-gbo ni nwọn ngbọ irohin nipa Ilewe-giga ti Nsukka, ti Ibadan ati eyiti nwọn şẹse da silẹ ni Ile Ifẹ pẹlu i Eko.

"O tun ku ọpọlọpọ awọn nkan ilosiwaju ti awọn ara Ipinlẹ Ariwa nfẹ ki awọn alakoso Ijọba ibẹ ṣe fun awọn ti a fẹ ki ẹ ma ba wa tẹnu mọ nigbagbogbo fun wọn. Tabi ẹ kò mọ wipe awọn alakoso Ijọba wa na nka iwe irohin yin? Nwọn ni awọn akọwe ti o gbọ ede Yoruba daradara ti o ntumọ wọn fun wọn lọsọse nitoripe awọn na nfẹ mọ n n ti awọn enia nro si iş ijọba ti ẹ fun wọn se."

### Alaye Olotu

Ọrọ ni ẹ gbọ yi, ẹnyin ọkawe wa. Eleti-Ọfẹ d'ara-ba, tete sare lọ ra tirẹ. Bi iwọ ti nfẹẹ ni awọn elomiran nfẹ ẹ.

— OLOTU

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries

Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.
Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.
HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

### Oba Tuntun Gori Ite Nilu Awon Tapa

BIDA — Gbogbo awọn Tapa ti nwọn mbẹ ni idalẹ ni nwọn wa si ilu Bida ni ijeje tişe ọjọ kẹta oşu ti a wa yi lati wa wo Ọba wọn tuntun se a ... igori itẹ; orukọ Ọba tuntun na ni Alhaji Usman Sarki ti o nşe Minisita ... ojuto eto iṣẹ Ijọba Apapọse ni arin ilu Nigeria l'Eko ri.

Gomina Ipinlẹ Ariwa, Ọlọla Kashim Ibrahim ni o gbe ọpa-aşẹ fun Ọba tuntun awọn Tapa na; Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa, Ọlọla Alhaji Ahamadu Bello, Sardauna Sokoto paapa wa nibẹ.

Ategun pẹlu oju ọrun ti ko dara lọjọ na ni ko jẹ ki awọn ikọ, awọn minisita ti Ijọba Apapọşe l'Eko nran lọ si Bida fun ẹyẹ igoritẹ na le de ibẹ nitoripe nigbati ọkọ ofurufu ti o nko wọn lọ de ibiti yio gunlẹ si ni Bida, dẹrẹba ti o nwa ọkọ aropileni na ko riran ri ilẹ ra-ra, o si poyi-poyi titi fun iwọn nkan bi wakati kan.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI—OFE

[illegible] KO ṢE WI [illegible]EJO
EDITORIAL [illegible] & WORKS CABLE & TELEGRAM
28 [illegible] Street, Lagos. "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV No [illegible] SATURDAY MAR 9th MARCH, 15th 193


## Awon Tisa Onigbanjo

Ẹnik e ninu awọn obi ti nwọn fi ọmọ si ile-ẹkọ ti o ma nka iwe irohin wa lọsọsẹ fi iwe kan ranṣẹ si wa ninu ọsẹ ti o kọja, ẹda iwe rẹ na ni a si tẹ si apa kan iwe yi. Ọrọ ti arabinrin na fẹnu kan ni ọrọ awọn alaṣẹ ile-iwe ti o dabi eni wipe nwọn fun awọn BABA ONILEWE ni anfani tabi aṣẹ lati ma lọ owo gba lọwọ awọn ọmọ ti nwọn nwa si ile-ẹkọ wọn nipa pe ki nwọn ma sọ fun wọn wipe ki nwọn mu owo wa loni, ki nwọn mu owo wa lọla lati ra irakura.

O ti di igba gbogbo ti awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ti nte mọ ẹnyin ọkawe wa leti wipe aiye ti di aiye eru. Eru na lo si ku ti olukuluku fi mba jẹun lode oni, bi ko ba nṣe bẹni kilo ba awọn tiṣa ti a ko awọn ọmọ fun wi pe ki nwọn ma kọ wọn lẹkọ debi ọrọ onigbanjo tabi iṣẹ alonilọwọgba ?

### Ẹgbe Obi

Ọpọlọpọ igba ni a si ti nte mọ awọn obi leti wipe ki awọn na lọ da ẹgbẹ obi (the Assciation of Parents and Guardians) sile ki nwọn le ma ba Ijọba ṣọro lori nkan ti o jẹ mọ ẹko awọn ọmọ wọn.

Iru ẹgbe bayi dara pupọ ni arin ilu ju ẹgbẹ a nda aṣọ-ẹbi lọ; O dara ju ẹgbẹ a nlọ jo aro ati ṣẹkẹrẹ lọ. Nwọn ni onise ni nmọ atiṣe ara rẹ.

### Eto Ilewe

Ki a wa ba ẹnyin akọwe ile iṣẹ alamojuto eto ẹkọ soro alajọba ẹ ko le fọwọ sọ aya wipe ẹ ko mọ wipe ọpọlọpọ awọn tiṣa ni o ngba owo ti ko tọna lọwọ awọn omọlewe won loṣoṣu. Owo yi pọ paapa ti o tile nni awọn obi lara ju igbati nwọn nsanwo ilewe lori awọn ọmọ wọn lọ.

Eleyi ko ba oju mu rara, o dabi ẹni wipe aiye yẹ wa pupọ nigbati awọn Oyinbo njọba lori wa ju asiko isisiyi lọ. Ko tile yẹ ki o jẹ wipe awọn alara ni a o ma yọ ara wa lẹnu.

Ominira ni a sọ wipe a nfẹ, kise omi-inira, nitorina ki a wo ọrọ na se fun ara wa, ki a ye yọ ara wa lẹnu. Iwa alonilọwọgba ko yẹ awọn olukọ awọn ọmọ wa.



M. T. Mbu

### Ogbeni M. T. Mbu

Aworan yi ni ti Ogbeni Matthew Mbu, Minisita ti awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe l'Eko ran gẹgẹbi ikọ Ijọba lọ si ipade nla ti nwọn nṣe ni ilu Geneva lori ọrọ ki nwọn yee ṣe nkan ija ogun. Nigbati ọrọ fẹ di koko, o sare pada wa sile lati wa gba imọran lọwọ Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa, o si ti pada ni arọ ijẹrin si ilu Geneva lati ma ba wọn ṣe ipade na.

# Iwe Si Olotu

## Ile-kewu Ilorin

A ri ka ninu iwe irohin yin laipẹ yi wipe nwọn ṣeṣẹ ṣi ile iwe giga kan ni ilu Ilọrin nibiti nwọn yio gbe ti ma kọ awọn ọdọmọde ni kewu ijinlẹ.

Ẹ jọwọ, mo fẹ mọ boya nwọn a tun mọ kọ awọn ọmọ ilekewu na ni awọn ẹkọ miran ti o yatọ si ede Larubawa (Arabic) tabi kewu yi nikan ni nwọn a ma kọ wọn?

Ẹ jọwọ ẹ la ọrọ ilekewu tuntun na ye wa, boya ọmọ awa na le fi awọn ọmọ wa ranṣẹ si ibẹ fun ẹkọ, awa ti a jẹ Musulumi ni mo wi o.

Emi ni,
Apapa Amusa Akanbi

ALAYE OLOTU : Awa na ko mọ orişirişi iru ẹkọ ti nwọn fẹ ma kọ wọn ninu ilekewu tuntun na sugbọn nkan ti a ṣe akiyesi ninu irohin ti akọwe wa fi sọwọ si wa ni ede Larubawa (Arabic) nikan ni nwọn a fẹ lati ma kọ wọn nibẹ. Paapa oruko ile ẹkọ na ti fi iru ẹkọ ti nwọn yio ma kọ wọn han gbangba-ilekewu.
—OLOTU

### Gbanjo Ni Ilewe

Mo ṣe akiyesi wipe laipẹ yi ni ẹ fẹnu kan ọrọ. Awọn olukọni, awọn tisa opurọ ti wọn nkọ awọn ọmọ isisiyi ni ọna eru ni ile ẹkọ, ti wọn nta iwe-ẹri (School Certificate) fun awọn ọmọ ti wọn ko yege ninu ẹkọ wọn ni ile iwe.

Mo gba fun yin fun eyi sugbọn o dabi ẹni wipe oju yin fo nkankan pataki ti o dabi aṣẹ ti awọ nijọba eleto ẹkọ awọn ọmọ wa fun awọn baba onilewe wipe ki nwọn ni anfani lati ma wipe ki awọn ọmọ na ma mu owo wa lati wa ra eleyi, wa ra tọhun nigbagbogbo.

Ko si bi o ti le ra iwe fun ọmọ rẹ to, awọn tiṣa yi ape otun ku. Titi ti ọdun yio fi pari ni nwọn npe awa obi wipe ki awa ma ra iwe fun awọn ọmọ ti aba fi sile ẹkọ.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa tọka aa yi si etigbọ awọn ijọba wa.

Eko Emi ni,
Iyaafin Ibidun Oshodi

### Iya Ajagbe Ilorin So Oro Iya

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe yin oloyinmọmọ lati kan saara si Iya Ajagbe ti o kọ iwe kan si ọmọ rẹ lati Ilọrin laipẹ yi nipa awọn oşişẹ ti o ko işẹ silẹ l'Eko.

Iya ni emi na, inu mi si dun pupọ nigbati mo ka iwe ikilọ ti iya na kọ si ọmọ rẹ.

Awọn agbalagba ni Ọlọrun ma jẹki agba ko lan ni orilẹ lailai. Bi ọmọde ba nhuwa awọn agbalagba a ti mọ ibiti iwa na a ru u de.

Ko si ẹnikan ninu awọn obi ti yio jẹ ki ọmọ on sọnu nipa iwa hihu. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe wahala awa obinrin pọ lori awọn ọmọ ti a nbi ? Diẹ ni ti ẹnyin ọkunrin lori awọn ọmọ na.

Ọlọrun jẹki awọn ọmọ na ma gbọ ti wa o.

Emi ni,
Iya Ibeji
Lafiaji,
EKO

**E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe ni osose fun irohin aladun lati Ipinle Ariwa wa lati odo Malam Shewu akowe irohin wa ti o nwa ni Oke Oya**

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### Egbe Alhaji

Nwọn niki a jọ rin pọ nṣe ni o nyẹ ni, iyen ni ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alhaji ilẹ yi (Zumat) Lijad ti nwọn fi ọkan ninu wọn jẹ oye Balogun ni ọsẹ ti o kọja yi, ọrọ Alhaji Busari Ileyemi Oke ti gbogbo enia mọ adape orukọ rẹ ni "ỌLỌRUNSOGO" ni mo nsọ. Alhaji Busari jẹ ẹnikan ninu awọn ti o kọ lọ kọ ile si ibiti gbogbo yin npe ni Ọlọrunṣogo loni ni Mushin. Nigbana inu igbo ni ibẹ wa, ṣugbọn nigbati Alhaji Busari de ibẹ o sọ orukọ ile ti o kọ si ibẹ na ni ỌLỌRUNSOGO.

### "Olorunsogo"

Nitotọ ko si ẹniti ko fẹ ki Ọlọrun ko ṣe ogo fun on. Nitotọ Ọlọrun ṣe ogo fun Alhaji Busari ọmọ Ijaiye nitoripe nigbati o de ibẹ, o di Ọlọla, o di Oloye. Mo gbọ wipe awọn ara adugbo na tun fi oye kan pamọ ti nwọn yio fun un ni aipe yi. Eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ Alhaji ati awọn Musulumi Mushin fun un ni ọsẹ ti o kọja ka mama. Ki Anabi Ọba o g o ko nawọ asiki fun emi Ayiluka paapa ki nle lọ si Mẹka ati ilu ti nwọn npe ni Mẹdina na.

### Obi Onitsha

Ọrọ bi Obi bi Obi kiṣe yeyẹ fun awọn ara Onitsha, bi o ba ba wọn ni ale o nwọn a pa obi-abata fun ọ pẹlu atare diẹ; bi o ba gbe ilu wọn ti o si mọ iwa hu, nwọn a mu ọ de ọdọ babasalẹ wọn—OBI. Ọba Onitsha ni nwọn npe hẹ.

Mo ba Ọgbeni oga olopa atijọ, ONYEJEKWE, ti ẹniti o ṣe iwadi ọrọ oye Obi ni aipẹ yi ni ilu Onitsha ni on ni Oye OBI tuntun na tọ si, yọ pupọ, ṣugbọn bawo ni ẹ o ti ṣe ọrọ Ọgbeni Enwezor ti o ti wọ "ipebi" ṣaju Onyejekwe si ? Mo gbọ wipe awọn afọbaje ilu Onitsha ti fi igbakan fun ni iyẹ oye, o si ti ṣe gbogbo etutu ti Obi (Ọba) ni lati ṣe.

Nigbati awọn alabẹ sekele fi abẹ wọn ge ọrọ Obi ni Ẹnugun yi ewo ni Ọgbeni Enwezor yio ṣe ? Yio gba kamu ni. Boya nwọn si le fi jẹ oye abọbajiroro tabi Oyin Onitsha. Ọrọ na a wu ko to bẹ.

### Oba Adele Mbo

Mo ti lọ si ọdun ni Eko lati wo ere awọn elesin ti pẹ, ṣugbọn mo ro wipe mo ni lati ba Ọba Adele pẹlu awọn Oloye rẹ lọ si ibi ere ẹsin na loni nitoripe mo gbọ wipe awọn gbajumọ wa fẹ fi ọjọ oni da ọba na pẹlu awọn Oloye rẹ lọla, wọn yio si gba wọn ni alejo. Ọlọgbọn d'ori eja mu, ẹ jọwọ emi na aba yin lọ sibi ere na, ki ẹ j'ọwọ ki ẹ ba mi wa ijoko-aga ti o yẹ mi.

### Ija Tiger

Mo gbọ wipe awọn Olotu Ijọba wa ti ṣe ipinnu lati na owo gọboyi (nkan bi ẹgbawa pọnun £20,000) lori ija ti nwọn fẹ ki Ọgbeni Tiger wa ja nilẹ yi pẹlu Oyinbo ti o mba du ipo "mo le na ẹ ni a na jẹ eti". Enyin ọkawe mi ẹ o ri iran wo lọjọ ti nwọn ba fẹ ja ija na, ṣugbọn ẹniti ko ba lowo ko ni ba wa de ibẹ, ogun ọkẹ ṣile (pọnun marun) kiṣe ọmọde owo.

### Aseyin

Ọrọ Ọba Obi Onitsha ti mo mu ẹnu kan ninu ọrọ mi ọsẹ yi jeki tuniran ọrọ iwadi ti Ijọba Ipinle Iwọ Orun ni awọn fẹ ṣe lori ọrọ Rai Adugwude, Aseyin tuntun ti awọn ara Iseyin fi ṣe Ọba ipinle ilu Aseyin atijọ; nwọn ni awọn fẹ rọ bi o ba ti ẹniti o yẹ ninu awọn ọmọ-oye ni awọn ajọbaje fi s'ori oye.

Isẹyin ọmọ abedi, ilu eyẹ kiki egun, ilu ti oju bu ni ti o ju ẹnu lọ, ọrọ re o, gbogbo enyin ọmọ Isẹyin ti ẹ wa ni idalẹ bi Eko, Ibadan ati Abẹokuta, o yẹ ki ẹ tete yan enia ki nwọn lọ si ile lọ sọ tenu wọn.

Ko si ọran wipe a mbẹru nibẹ, alado ti o wa nidi ọrọ na ni Ijọba fẹ hu jade o si yẹ ki o ran wọn lọwọ ki awọn le ri idi otitọ na. Otitọ ni yio leke.

### Ghana Nronu

Ni ijerin ọjọ'Ru ni o di ọdun kefa ti awọn ara ilu Ghana ti gba Ominira, ṣugbọn dipo ki nwọn gbe ilu sita ki nwọn ma jo ki nwọn ma yọ nwọn ni ẹdun awọn ti jamba bombu pa nigba kan ni awọn yio fi ọjọ na ṣe ikẹdun fun. Ọrọ na dun ẹni Ayiluka nitotọ ṣugbọn wahala ko ti tan nilẹ ni Ghana. Dokita Nkrumah nibo ni ẹ fi t'awọn ti nwọn ku si ipamọ ninu ọgba ẹwọn si ?



**Aworan yi ni ti awon omo ilu Nigeria meji akeko ni'ilu London lojo ti nwon lo wo bi awon Oyinbo ti nse nsoro ni ile Igbimo Asofin ilu Gesi. Oruko awon akeko meji na ni Ogbeni Kolade Adeyoju ati Omidan Anzaka Uwechia Lati Ipinle Iwo Orun ni nwon ti wa keko ni ilu Oyinbo.**

# Alhaji Busari "Olorunsogo" Se Iwuye

MUSHIN — Gbogbo orişirişi awọn ọmọ ẹgbẹ Ijaiye lati Abẹokuta, Ibadan ati Eko ni nwọn pese si ibi aşeyẹ iwuye ti ALHAJI BUSARI ILEYẸMI ỌKẸ, ẹniti gbogbo awọn ara Mushin mọ Oju Owoye mọ adape orukọ rẹ ni "Alhaji ỌLỌRUNSOGO", ti şe ni ijeje ọjọ Sunday ni ojude ile rẹ. Lawani Oye meji ni nwọn we fun Alhaji Busari lọjọ na gan, ekinni ni ti oye Seriki Musulumi; fun awọn janmọ Mọşalaşi Jimọ Musulim ekeji ni oye Balogun ẹgbẹ awọn Alhaji (Zumat Lijad) ti awọn Alhaji fi jẹ.

Ẹyẹ a nwe lawani ti oye Balogun ni awọn Alhaji kọ se fun ni ile rẹ ni Ọlọrunsogo ẹniti o si we lawani na fun ni Lemọmu - agba Alhaji Yesufu Arikewuyọ) ẹniti o si şe ekeji rẹ ni Olori Ratibi, Alaji Akorohufayọ. Awọn enia jankan jakan ni nwọn si şe alaga lọjọ na. Awọn bi Alhaji L.A. Amọdu, (baba ẹgbẹ) Ọgbẹni Lawal, adajọ Kotu Şomolu, Oloye V.A. Ilọri, Arẹ Ẹgba l'Abẹokuta tişe Balogun fun gbogbo awọn ọmọ Ijaiye, Oloye Lawidi Ẹkẹrin.

Alhaji Lemboye, Alhaji S. Auelabu, Alhaji Shitu Seriki lati Ọtta, Alhaji L.A Ajagbe, Alhaji A. F. Masa, alaga ile Igbimọ Minisfa Eko, Seriki Adamu Animashaun tişe baba ẹgbẹ Mọşalaşi 'Jimọ Ajumọni ni Mushin, Alhaji Imam Tijani Alhaji Imam Amusa Akindele, Alhaji TS Kaffo Alhaji Jaji, igba keji alaga ẹgbẹ awọn Alhaji, Alhaji Bakare, Alhaji Shekoni, Olori awọn Oniwasi, Alhaji T.S. Diko, awọn Alhaja Nimọta Saba, Alarape ati Nimọta Ligali.

Ẹyẹ ọjọ na dun pupọ, awọn enia pọ bi yanrin; bi nwọn ti we Lawani ti oye Balogun awọn Alhaji fun Ọgbẹni na tan ni gbogbo awọn ẹb. ati ọrẹ wa tẹle lọ si Mọşalasi Jimọ Mushin fun eto lati we Lawani oye Seriki ti awọn Musulumi Mushin fi i jẹ. Tijo tayọ ni nwọn si fi pade wọn lọna. Lemọmu agba si paşẹ fun Olori Ratibi pe ko we lawani fun oloye na lẹhinti nwọn ti sọrọ didun didun nipa iwa Alhaji Busari larin awọn janmọ tan.

Lẹhin eyi gbogbo awọn enia ti o wa si ibi aşeyẹ iwuye na wa pada si adugbo Ọlọrunsogo nibiti Oloye na ti fi nkan jijẹ ati mimu tẹ gbogbo enia lọrun. Gbogbo awọn iyawo rẹ, ni wọn fi ile pọn'ti ti nwọn f'ọna roka.

Awọn diẹ ti a raye lati darukọ ninu ogunlọgọ awọn enia ti nwọn wa lati Ibadan, Abẹokuta, ati Eko ni Oloye Gbadamọsi, Ọttun Ijaiye, Oloye J.K. Ajala, Oloye A. Laleyẹ, Oloye S. Fashola, S.A. Adediran, Alhaji R Baiyewu, Shittu Agboọla, Oloye Ladapọ, Alhaji Laguda Bada Eko, Alimi Olori, Gbadamọsi Balogun Ọrẹdẹgbẹ, Y S Anifowose, B A Ọlayọri, T S Diko Iya-afin Birikusu Oluwo ya Jẹlili, Sule Ọşọ ati Yesufu Onifade.

Oye na a mọ ori o.

# Oba Tuntun Gori Ite Nilu Awon Tapa

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

nigbati ko ri ọna ba a wọ ni o ba pada si ibiti o ti gbe ra ni Ikẹja.

Ninu awọn Minisita mejidinlogun ti nwọn yan gẹgẹbi ikọ lati şe aşoju Ijọba Apapọşe ni Oloye J.M. Johnson, Oloye Festus Okotie-Eboh, Alhaji Inua wada, Alhaji Yusufu Maitama Sule, Dokita Mbadiwe pẹlu awọn meji ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun yan lati Ibadan.

Aşeyẹ Oye Ọba tuntun na dun pupọ, awọn Tapa lọkunrin ati lobinrin lo gbe ilu bẹmbẹ lọ sibẹ lati fi şere fun un.

PHILIPS
for RADIO
PHILIPS



# Nibo Lo Da, Baba Onimoto?

**Aworan omode kan ti o nje Andrew Kear ni e nwo yi ninu moto elere ti nwon nfi sare nibiti o gbe ti mba Olopa kan soro pe on na ti dagba to lati wa moto sare idije agbaiye ti awon ogunnagbogbo fe sa laipe yi. Moto Jagua dabi iru eyiti awon Oy'nbo Gesi ti o nse moto ta gbe jade fun ifihan nilu kan ti nwon npe ni Brighton. Iru moto kekere ti e nwo yi nwon le lo epo petiro tabi eletiriki fun nu.**

# World Audience For Nigerian Composer

LONDON — Listeners to the B.B.C. all over the world will hear the first radio performance of an aria from a young Nigerian musician's Christmas oratorio composed while studying in Britain.

The composer is Ayo Bankole of Lagos, formerly assistant organist at the Cathedral Church of Christ and a member of the staff of the NBC. Now Organ Scholar at Clare College, Cambridge Bankole's oratorio was first sung in Yoruba–by the College choir, and much admired by all who heard it including the College Chaplain, the Rev. J.O.C. Alleyne.

Bankole, who started his advanced musical training in Britain in 1957 at the Guildhall School of Music in London, won the Clare College Organ Scholarship in 1961 and is now in the second year of a B.A. degree course.

"As Clare Organ Scholar I am responsible for arranging, in conjuction with the chaplain, all the music for the daily chapel services and for the full choral services held three times a week", he explained.

"With others music scholars I plan concerts given by the College orchestra and occasionally act as conductor."

## Trade Chairman: Nigerian Rubber Is Superb

LONDON — The Nigerian rubber industry has made such outstanding progress that today the top grade of Nigerian rubber was "second to none," said the chairman of the Rubber Trade Association of London, Mr. N. W. Hoare, addressing the Association's annual general meeting last week. Only a few years ago Nigerian rubber production had been small and of quality "mostly very poor indeed.". But all this had been transformed.

"It is now a great pleasure to record the marked progress that the Nigerian rubber producing industry has made, particularly the improvement in quality and grading." said Mr. Hoare.

He had been informed by several buyers that top grade Nigerian rubber was as good as any produced anywhere.

Figures published in Britain by the International Rubber Study Group show that the production of synthetic rubber rose in 1962 by 280,000 tons to a total of 2,240,000 tons, and that consumption, at 2,142,000 tons was up by 252,000 tons.

The upward trend in consumption of both types and growing competition between natural and synthetic must be expected for the future, but the fact was that natural rubber remained the better article, said Mr. Hoare.

"It has continued to be bought although there has been a super-abundance of cheaper synthetics," he stated.

## American Geographer Calls Africa 'Land Of Promise'

Newark (New Jersy) —An American geographer who has lived and worked in Africa calls the continent a place of "change and promise where dedicated leaders are struggling to solve huge problems."

She is Dr. Ann L. Kolars, assistant professor at Rutgers University's Newark College of Arts and Sciences. She has studied life in Uganda, Tanganyika and Kenya at close range. "The African people are the most educated minded I have ever met," Dr. Kolars said in an interview puplished in the Newark Star Ledger.

The American geographer made her first visit to Uganda in 1956 to study its agriculture. She returned to Africa in 1959 with her husband, Dr John F. Kolars, also a geographer and a Rutgers University professor to study in Tanganyika and Kenya.

Dr. Kolars and her husband met while they were graduate students at the University of Chicago. At that time, they mapped out their areas of specialization–hers was to be Africa, his the Middle East.

## More British Bicycles Sold In Kenya

NAIROBI–British exports of bicycle to Kenya rose by 4,000 units last year, compared to 1961 figures. Total figures for 1962 were 18,652 bicycles. Bicycle sales to all parts of the world last year were worth £11,435,000.



## Mr. Duncan Sandys In Kenya For Constitutional Talks

Mr. Duncan Sandys (right), Secretary of State for Commonwealth Relations and the Colonies, talking during a break in the Kenya constitutional conference with, left to right: Governor Malcolm Mac Donald, Mr. Ronald Ngala, president of the Kenya African Democratic Union, and Mr. Jomo Kenyatta, president of the Kenya African National Union.

The talks in Nairobi are concerned with the colony's independence. During his visit to East Africa, Mr. Sandys planned to visit Zanzibar, Tanganyika and Uganda.

## Fagbure Onirohin Ijoba Nilu Oyinbo Ti De

EKO — Ọgbẹni Gabriel Fagbure tiṣe alaṣẹ eto ikede Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria ti o nṣe iṣe ni ile Ijọba na ni ilu Oyinbo (London) ti de si Eko yi ni aipẹ yi; o ni on ko ṣe iṣẹ ọba mọ, on na ti toju bọ fun ara on.

Ọdun mẹfa gbako ni Ọgbẹni Fagbure fi wa ni ilu Oyinbo nibiti o gbe nṣe irohin ikede iṣẹ Ijọba ilẹ wa, o si fi ọpọlọpọ igba rin irin ajo lọ si orisirisi ilu ni ilu Oyinbo na. Ṣaṣa nibi ti ko de nigbati o wa nibẹ, eleyi si tun fun ni imọ kun imọ rẹ.

Ayiluka "Eleti-Ọfẹ" ni on gbọ wipe iṣẹ a ngba irohin fun enikeni ni Ọgbẹni Fagbure fẹ pada si. Mo gbọ wipe o ti ri ibikan ni opopo Ọdunlami leti Ṣọṣi awọn ọmọ ologun igbala (Salvation Army) ti yio fi ṣe ile iṣẹ rẹ tuntun na.

Ki Ọgbẹni Fagbure to wọ iṣẹ Ijọba lọ si ilu Oyinbo, Olotu iwe irohin West African Pilot ni on ṣe ni Yaba. Gabriel, awa eniwe irohin "Eleti-Ọfẹ" ki yin, ẹ ku abọ, ọna ala, a o si ma ri ṣe o.

# Akowe Igbomina Parapo Farakorin Lori Oro Oba Ilorin

ILỌRIN — Gbogbo inu Kotu nla ni Oke Oyinbo ni o kun fofọ fun awọn ara ọrẹ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ ti nwọn wa gbọ bi adajọ Kotu nla na yio ti da ejọ Ọgbẹni kan ti nwọn pe orukọ re ni Joseph Idowu Adukoko tiṣe akọwe eto ẹgbẹ Igbomina Parapọ dapọ mọ ẹgbẹ Oṣelu NPC (ẹgbẹ Olomi) ni agbegbe Ilọrin ti nwọn ni o ba orukọ Ọba Ilọrin, Mallam Sulu Gambari" jẹ.

Ẹsun ti nwọn fi Adukoko sun ni pe nigba kan ti Ọba Ilọrin fẹ se aṣeyẹ kan o ranṣẹ si gbogbo awọn Oloye ni igberiko kakiri wipe ki nwọn wa ba on ṣe e. Ẹjọ ti nwọn romọ Adukoko, akọwe Igbomina Parapọ, ni pe gbara ti o ti gbọ wipe awọn Oloye yi nfẹ wa silu lati wa ba Ọba na ṣe eyẹ ni o ti gbe ra, ti o ti gba ọdọ wọn lọ, ti o ni ki awọn ma lọ nitoripe ọba na ti po egbogi ti yio fi ra wọn niye m o n jẹ fun wọn, bọọ bọọ ni nwọn yio si ma wo bi aṣuntan, nwọn ko ni le bere Ipinlẹ ti nwọn mbere lọwọ awọn ara Ilọrin mọ rara.

Nigbati nwọn kọ ro ẹjọ na ni Kotu Alikali, ewọn ẹdun kan ni Alikali ju Adukoko si ki o to sọ wipe idajọ na ko te on lọrun, ni nwọn ba tun gbe ẹjọ na lọ si Kotu loke Oyinbo ki nwọn to sọ wipe ki akọwe ẹgbẹ Igbomina Parapọ na lọ san ọgọrun pọnun (£100 s ra si Kotu fun isọkusọ ti o sọ na.

Lọya C. A. Adefarasin ti o wa ni Ọffa ni o ṣe agbejọro fun Adunkoko lori ẹjọ na.

## Opo Kan Gba Owo Lori Obe

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Obinrin opo yi ṣe bayi fun ọdun mẹrinlelo ... gbako ti awọn mejeji jọ nrin pọ, sugbọn ọkunrin yi ko gbe e ni iyawo titi ti o fi jalaisi ni iwọn nkan bi ọdun keji nisisiyi.

Nigbati opo-ọkunrin yi ku o fi eru ti o joju ... silẹ; nwọn ni awọn 'dukia' ati owo ti o fi silẹ di ... diẹ ni ẹgbaata pọnun (£6,000).

Eleyi mu ki obinrin opo ti t'on pẹlu rẹ jọ nṣe ikẹ ara wọn fun nkan bi ọdun mẹdọgbọn kawọ le'ri to awọn alakoso Ijọba ilu ti nwọn ngbe lọ wipe ki nwọn gba on, gbigba ni nwọn ngba alailara.

O ni bayi kọ ni on ati Albert jọ fọrọsi, o ni adehun ti o wa larin awọn ni wipe on (Opo ọkunrin) yio gbe on ni iyawo, iyen ni o si jẹki on ma tọju rẹ, ti on si nse ọbe fun un.

Nwọn gbe ọrọ na lọ si Kotu ni iwaju adajọ, asẹhinwa asẹhinbọ nwọn ni ki nwọn fun obinrin opo yi ni ẹgbẹsan pọnun o din mẹdogun (£1,785) ninu ogun ti Ọgbẹni Beckitt, eni ọdun mẹrinlelа-dọrin (74) fi silẹ.

## Awolowo Yio Dahun Gbogbo Esun Re

(O bere loju ewe kinni)

Bi o ti sọ eyi tan ni awọn lọya agbẹjọro wọn dide, nwọn ni ki adajọ ko jọwọ ki o sun ẹjọ na siwaju, ki o fun gbogbo wọn ni aye lati ribi jiroro lori ẹjọ ti nwọn fẹ ro pẹlu awọn ẹleri ti nwọn fẹ pe; awọn si fẹ ki adajọ gba iduro fun gbogbo wọn.

Adajọ ni ti o ba di Tuesday ọjọ mẹrin loni ki nwọn wa gbọ esi on lori awọn ibere mejeji na.

## O Ya Kalo !



"O ya ka lọ wẹ," bẹni arabinrin yi wi bi o ti ngun atẹgun lọ si isalẹ omi lati lọ wẹ nibiti nwọn gbe nfọnti sere. Awọn Oyinbo fẹran omi pupọ, bi otutu ti wu ki o mu to ninu oṣu May ati June nwọn a lọ luwe lodo.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Lagos.